# ÌTÀN ÌJÌNLẸ̀ NÍPA ÌSỌTẸ́LẸ̀

## PÍPADÀ SÍ JERUSALẸMU

## Ìtàn ...

**Luku 24:13-35**

Awọn ọmọ-ẹ̀hìn Jesu wà ninu ìbẹ̀rù ìparun nlá. Gbogbo ìrètí àti àlá wọn niti ìjọba Ọlọrun titun ni a ti kàn mọgi ni ọjọ́ Friday (Jímọ̀) tó kọjá. Cleopas ati awọn akẹgbẹ́ rẹ̀ nrọra nlọ lati Jerusalemu sí ìletò kékeré kan, ti a npè ni Emmausi pẹ̀lú ìbànujẹ́ ati ipòruru ọkan. Ó sì ṣe, bi oòrùn ti nwọ̀ ni ọjọ́ Àìkú (Sunday) náà, awọn ọmọ-ẹ̀hìn sì nrìn lọ ni ojú ọ̀nà, alejò kan súnmọ wọn lati ba wọn rìn. Wọn kò mọ̀ pé ẹnito nbá wọn rìn ni Oluwa funrara Rẹ̀, to jí dìde.

Wọn kò fiyesi ẹni to nbá wọn rìnrìn àjò yi, awọn ọmọ-ẹ̀hìn mejeeji yi nsọ̀rọ̀ nípa ohun tó sẹlẹ̀ ni ọ̀pin ọ̀sẹ̀ náà, wọn nrọra nlọ láìní ìrètí kankan. Bẹ̀ẹ̀ni Jesu ntẹ́tí si wọn, kò sì tètè fi ara Rẹ̀ hàn fun awọn ọ̀rẹ́ Rẹ̀ ti kò nírètí mọ yi. Ṣùgbọ́n Jesu mọ̀ọ́mọ̀ fi ara pamọ́ fun wọn nitori pé nibayi, wọn nílò lati mọ Ìwé Mímọ́. Bí o ba ṣepé Jesu jẹ́ kí awọn ọmọ-ẹ̀hìn meji wọnyí mọ̀ pé oun ni Jesu ni, wọn ìbá yọ ayọ̀ àyọ̀jù débi wípé wọn kò ni leè gbọ òtítọ́ tó ṣe pàtàkì ti Ó fẹ fi fun wọn.



Bí o tilẹ̀ ṣe pé wọn ti tẹ́tí sí ẹ̀kọ́ ati ìwaasu Rẹ̀ fun bi ìwọn ọdún mẹta ààbọ̀, síbẹ̀ wọn o ti mọ ohun ti iṣẹ́-ìránṣẹ Jesu jású. Ó ti sọ fun wọn gbangba pé, "A o fi Ọmọ-eniyan le awọn eniyan lọ́wọ́, nwọn o sì pa á; lẹhin ìgbàtí a bá sì pa a tán, yio jinde ni ijọ́ kẹta. Ṣùgbọ́n ọ̀rọ̀ naa kò yé wọn, ẹ̀rù si bà wọn lati bi i léèrè." Marku 9:31,32.

Jesu sì rọra dá sí ọ̀rọ̀ wọn, Ó sì fun wọn ni kọ́kọ́rọ́ lati mọ gbogbo Ìwé-Mímọ́ ati ìsọtẹ́lẹ̀ níwọ̀n wákàtí meji.

AMAZING FACTS

# Ẹ̀kọ́

Dí àwọn àlàfo wọnyí, lẹ́hìn tí o bá ti kà ẹsẹ Bibeli kọọkan tán.

1. Melo nínú Ìwé Mímọ́ ni a pa láṣẹ fun wa lati gbàgbọ́?

   **Luku 24:25**
   O sì wí fún wọn pé, Ẹnyin ti oye kò yé, tí o si yigbi li àyà lati gba _________ èyí ti awọn woli ti wí gbọ́.
   **2 Timoteu 3:16**
   Gbogbo __________ li o ní ìmísí Ọlọrun, ti o si ne èrè fún ẹ̀kọ́, fun iba-ni-wí, fun ìtọ́ni, fun ìkọ́ni ti o wà ninu òdodo.

Àkíyèsí: Àṣẹ Ọlọrun (òtítọ́ mímọ́) tó pé, tí kò sì leè yẹ̀ ló wà nínú Majẹmu Lailai ati Majẹmu Titun. Kọ́kọ́rọ́ lati ní òye awọn asọtẹ́lẹ̀ inú Ifihan ni a rí ninu awọn ìtàn tó wà ninu Majẹmu Lailai. Fún apẹrẹ, ninu àwọn ẹsẹ mẹrin le ni irínwó (èòè) tó wà ninu ìwé Ifihan ló jẹ́ wípé irínwó ó dín meji-le-lógún ninu wọn, ni a mu jáde lati inú awọn ìtàn ati isọtẹ́lẹ̀ inú Majẹmu Lailai.

2. Fun awọn wo ni Jesu sọ wípé, a fi Ìwé-Mímọ́ hàn fún?

   **Luku 24:27**
   Ó sì bẹ̀rẹ̀ lati Mose ati gbogbo awọn woli wá, o si túmọ̀ nkan fun wọn ninu ìwé-mímọ́ gbogbo nípa ti ara _____.
   **Johannu 5:39**
   Ẹnyin nwá inú ìwé-mímọ́ nitori ẹnyin rò pé ninu wọn li ẹnyin ni ìyè ti kò nipẹkun; wọnyi si li awọn ti njẹri ____.
   **Ifihan 1:1**
   IFIHAN ti _________ _________, ti Ọlọrun fi fun un, lati fihàn fun awọn ìranṣẹ rẹ̀ ohun ti kò le ṣàìṣe ni lọọlọọ; o si ranṣẹ, o si fi i hàn lati ọwọ́ angẹli rẹ̀ wá fun Johannu, iranṣẹ rẹ.

Àkíyèsí: Àárín gbùngbùn Ìwé-Mímọ́ ati isọtẹ́lẹ̀ ni Jesu. Ẹ̀kọ́ yi yio ṣe àlàyé lorí àkórí asọtẹ́lẹ̀ púpọ̀, ṣùgbọn máṣe gbàgbé wípé, àfojúsùn Danieli ati Ifihan ni Jesu Kristi ati Ìjọba Rẹ̀.

3. Orúkọ wo ni a tún lò fún Jesu nínú Bibeli?

   **Johannu 1:1**
   LÍ àtètèkọṣe li _________ wà, Ọ̀rọ̀ sì wà pẹlu Ọlọrun, Ọlọrun sì li Ọ̀rọ̀ naa.
   **Johannu 1:14**
   ________ naa si di ara, oun si mba wa gbé, (àwa si nwò ogo rẹ̀, ogo bi ti ọmọ bíbí kanṣoṣo lati ọ̀dọ̀ Baba wá,) o kún fun oore-ọ̀fẹ́ ati otitọ.

4. Irú awọn eniyàn wo ni Ọlọrun lò lati kọ Bibeli?

   **2 Peteru 1:21**
   Nitori aṣọtẹ́lẹ̀ kan kò ti ipa ìfẹ́ eniyan wá ri; ṣùgbọ́n awọn eniyan __________ Ọlọrun nsọrọ lati ọdọ Ọlọrun bi a ti ndarí wọn lati ọwọ́ Ẹmí Mímọ́ wá.

5. Dídá Jesu mọ̀ lo ma nmú ìyè àìnípẹkun wá (Johannu ẹ́í:é). Bàwo ni Jesu ṣe di mímọ̀ fun awọn ọmọ-ẹ̀hìn Rẹ̀?

   **Luku 24:35**
   Nwọn sì ròhìn nkan ti o ṣe li ọ̀nà, ati bi o ti di mímọ̀ fun wọn ni _____ ______.

Àkíyèsí: Nínú Bibeli, àkàrà dúró fun Ọ̀rọ̀ Ọlọrun. Jesu wípé, "A ti kọwé rẹ̀ pé, Eniyàn ki yio wà láàyè nipa àkàrà nìkan, bíkòṣe nípa gbogbo ọ̀rọ̀ ti o ti ẹnu Ọlọrun jade wá." Matteu è:è. Bí a se nka, tí a sì nlò ati bi a ti ntẹ̀lé Ìwé-Mímọ́, a o ni agbára, ayọ̀, alaafia, ati ìyè ainipẹkun.

6. Bàwo ni Bibeli ṣe gbọ́dọ̀ ṣe pàtàkì sí kristiani tó?

   **Jobu 23:12**
   Bẹ̀ẹ̀ni emi kò padà sẹ̀hìn kúrò ninu òfin ẹnu rẹ̀, emi sì pa ọ̀rọ̀ ẹnu rẹ̀ mọ́ _________ òfin inú mi lọ.
   **Orin Dafidi 119:105**
   Ọ̀rọ̀ rẹ ni _________ fun ẹsẹ mi, ati _________ sí ipa ọ̀nà mi.

Àkíyèsí: Ẹ̀ṣù korira Bibeli, yio sì ṣe ohunkohun lati dí awọn eniyan lọ́wọ́ ki wọn maṣe kà á. Ẹ̀ṣù mọ̀ wípé, awọn asọtẹ́lẹ̀ inu Bibeli ma ntú àṣírí ọ̀nà ti oun ma ngbà lati tan awọn eniyan jẹ. Nítori naa, máṣe jẹ ki o yà ọ lẹnu bi ẹ̀ṣù bá fẹ́ yi ọkan rẹ̀ padà kúrò ninu ẹ̀kọ́ yi tabi ti o ba fẹ́ fi ohun miran di ọ lọ́wọ́. Ọlọrun yi o la ọ̀nà fun awọn ti wọn nwá òtítọ́, ki wọn le è rí òtítọ́.

7. Taló ma nràn wá lọ́wọ́ lati mòye Bibeli?

   **Johannu 16:13**
   Ṣùgbọ́n nígbàtí oun, àní _______ otitọ́ nì bá dé, yio tọ́ nyin sí ọ̀nà òtítọ́ gbogbo; nitori kì yio sọ ti ara rẹ̀; ṣùgbọ́n ohunkohun tí o bá gbọ́, oun ni yio ma sọ: yio si sọ ohun ti mbọ̀ fun nyin.
   **Johannu 14:26**
   Ṣùgbọ́n Olutunu naa, ______ _______, ẹniti Baba yio rán li orukọ mi, oun ni yio kọ́ nyin li ohun gbogb, yio si rán nyin létí ohun gbogbo tí mo ti sọ fun nyin.
   **1 Korinti 2:13**
   Ohun náà ti awa ti nsọ, kì iṣe ninu ọ̀rọ̀ ti ọgbọ́n eniyan nkọ́ni, ṣùgbọ́n eyiti Ẹmí Mímọ́ fi _______; eyiti a nfi ohun Ẹmí we ohun Ẹmí.

8. Kíni mo le ṣe lati mọ̀ dájú wípé Ẹmí Mímọ́ ndarí mi nígbàtí mo ba nka Bibeli mi?

   **Luku 11:9**
   Emi si wí fun nyin, Ẹ _________, a o si fi fun nyin; ẹ wá kiri, ẹnyin o sì rí; ẹ kànkùn, a o sì sí i silẹ̀ fun nyin.
   **Luku 11:13**
   Njẹ́ bi ẹnyin ti iṣe eniyan búburú ba mọ̀ bi aati ifi ẹ̀bùn didara fun awọn ọmọ nyin: melomelo ni Baba nyin ti mbẹ li ọrun yio fi Ẹmí Mímọ́ rẹ̀ fun awọn ti o _______ lọdọ _______?
   **Johannu 7:17**
   Bí ẹnikẹni bá fẹ́ lati ṣe _______ _______, yio mọ̀ niti ẹ̀kọ́ naa, bi iba ṣe ti Ọlọrun, tabi bi emi ba nsọ ti ara mi.

Àkíyèsí: Ara iṣẹ́ ti Ẹmí Mímọ́ ma nṣe ni pé ki o ràn wá lọ́wọ́ lati mọ òtítọ́ tó wàn nínú Ìwé-Mímọ́. Ìdí niyi, ti a fi gbọdọ̀ kọ́kọ́ bèèrè lọ́wọ́ Ẹmí Mímọ́ lati darí wá, ki o tó di wípé a sí ìwé Ọlọrun. Mo le mọ̀ dájú wípé Ẹmí Mímọ́ ndarí Bibeli kíkà mi bi (ẹ̀) mo ba bèèrè pé, ki o darí mi ati (ẹ̀) bi mo ba fẹ́ lati gbà ati lati tẹ̀lé òtítọ́ bí Ó ba ṣe fi hàn mí.

**9.** Báwo ni gbígba àdúrà gidigidi kí a tó ka Bibeli ṣe ma nràn wá lọ́wọ́?
**Orin Dafidi 119:11**
Ọ̀rọ̀ rẹ ni mo pamọ́ li àyà mi, ki emi kí o ma ba ________ si ọ.
**Jeremiah 33:3**
Képè mi, emi o si da ọ ________, emi o si fi ohun nlá ati _________ hàn ọ ti ìwọ kò mọ̀.
**Romu 15:4**
Nítorí ohunkohun tí a kọ tẹlẹ̀, a ti kọ ọ fun _________ wa, pé nipa suuru ati ìtùnú ìwé-mímọ́ ki a le ni __________.
Jakọbu **1:5**
Bí ó bá ku _________ fun ẹnikẹni, kí ó bèrè lọ́wọ́ Ọlọrun, ẹniti ifi fun gbogbo eniyan li ọ̀pọ̀lọpọ̀, tí ki isi ba-ni-wí; a o sì fi fun un.

**10.** Ọ̀nà wo ni Bibeli là kalẹ̀ lati má a ka Ìwé-Mímọ́?
**Isaiah 28:10**
Nitori ______ lé àṣẹ, àṣẹ lé àṣẹ; ẹsẹ lé ẹsẹ, _____ lé ẹsẹ; díẹ̀ nihin, díẹ̀ lọhun.
**1 Korinti 2:13**
Ohun náà ti awa ti nsọ, kì iṣe ninu ọ̀rọ̀ ti ọgbọ́n eniyan nkọ́ni, ṣùgbọ́n eyiti Ẹmí Mímọ́ fi nkọ́ni; eyiti a nfi ohun Ẹmí ________ ohun Ẹmí.
**2 Peteru 1:20**
Kí ẹ kọ́ mọ̀ èyí pé, kò sí ọ̀kan ninu asọtẹlẹ inú ìwé-mímọ́ ti o ni ìtumọ̀ ______.

Àkíyèsí: A gbọ́dọ̀ kọ gbogbo ìmọ̀ ti ara wa sílẹ̀, kí a sì ma a ka Bibeli, kí a ka Ìwé-Mímọ́ lórí àkòrí kọọkan ("díẹ̀ nihin, díẹ̀ lọhun") àti wípé ki a sì má a fi ẹsẹ wé ẹsẹ. Kí a jẹ́ kí Bibeli sọ̀rọ̀ fúnrara rẹ̀. Níwọ̀n ìgbàtí a ba ti ṣe èyí, a o ma a rí òtítọ́ kedere. Ọ̀nà yí ni Jesu gbà lati fi yé awọn ọmọ-ẹhin Rẹ̀ lójú ọ̀nà Emmausi wípé Oun ni Messiah náà (Luku ẹ̀è:ẹ́ì).

**11.** Kíni Bibeli kíkà yio ṣe fun wa?
**2 Timoteu 3:15**
Ati pé lati ìgbà ọmọde ni iwọ ti mọ ìwé-mímọ́, tí o le sọ ọ́ di __________ si _________ nipasẹ ìgbàgbọ́ ninu Kristi Jesu.

Àkíyèsí: Ìwé-Mímọ́ ma n rani-lọ́wọ́ lati ní òye ètò nlá Ọlọrun ti ìgbàlà - èyí ti iṣe ìròhìn pàtàkì ti a fi fún awa ẹni kíkú.

**12.** Ní ìbámu pẹ̀lú ọ̀rọ̀ Jesu, níbo ni a ti rí òtítọ́?
**Johannu 14:6**
Jesu wi fun un pé, Emi li ọ̀nà, àti _________, ati ìyè : kò sí ẹnikẹni ti o le wá sọdọ Baba, bikoṣe nipasẹ̀ mi.
**Johannu 17:17**
Sọ wọn di mímọ́ ninu òtítọ́: òtítọ́ li ________ rẹ.

Àkíyèsí: A rí òtítọ́ ninu Ọ̀rọ̀ Ọlọrun - Bibeli. Òtítọ́ jẹ ohun tó sọ̀wọ́n ninu ayé loni, bẹ́ẹ̀ ni awọn eniyan si njìyà nitori òtítọ́ tí ó sọ̀wọ́n yi. Òtítọ́ nípa ohun gbogbo tó ṣe pàtàkì la rí ninu Ìwé-Mímọ́. Kíkà ati títẹ̀lé ìmọ̀ rẹ lo ma nsọ eniyan di ominira (Johannu 8:32) àti pe o nmú ayọ̀ wá, igbé-ayé ọ̀pọ̀ (Johannu 15:11).



**13.** Ìkìlọ̀ wo nípa Bibeli kíka ni a fun wa ninu Ìwé-Mímọ́?
**2 Timoteu 2:15**
Ṣaápọn lati fi ara rẹ hàn níwájú Ọlọrun li ẹniti o yege, aṣiṣẹ́ tí kò ni lati tijú, ti o _________ ọ̀rọ̀ òtítọ́ bi o ti yẹ.
**2 Peteru 3:16**
Bí o ti nsọ̀rọ̀ nkan wọnyi pẹ̀lú ninu ìwé rẹ̀ gbogbo; ninu èyí ti ohun miran tí ó ṣòro iyé ni gbé wà, eyiti awọn òpè ati awọn alaiduro nibikan _______, bi nwọn ti nlọ́ ìwé mímọ́ ìyókù, sí __________ ara wọn.

Àkíyèsí: "Pínpín ọ̀rọ̀ òtítọ́ bi o ti yẹ" tumọ̀ sí wípé ki a túmọ̀ ọ̀rọ̀ náà dáradára ati pẹlu òtítọ́. Ewu nlá nbẹ ninu lílọ́ Ìwé-Mímọ́ lati mu ki o sọ ohun ti a fẹ́ ki o sọ. Ohun tí mo sọ nípa Bibeli jẹ́ ohun kékeré. Ohun to ṣe pàtàkì ni ohun ti Ìwé-Mímọ́ ba sọ nipa ara rẹ̀.

**14.** Báwo ni a ṣe le è dán ẹ̀kọ́ awọn ẹ̀sìn gbogbo lonírúurú wò?
**Ise Awọn Aposteli 17:11**
Awọn wọnyi sì ní ìyìn ju awọn ti Tessalonika lọ, niti pé nwọn fi tọkàntọkàn gba ọ̀rọ̀ náà, nwọn si _______ inú ìwé-mímọ́ lojoojumọ́ bi nkan wọnyi ri bẹ́ẹ̀.
**Isaiah 8:20**
Sí _______ ati sí _______: bi nwọn kò ba sọ gẹ́gẹ́ bi ọ̀rọ̀ yi, nítori kò sí _________ ninu wọn ni.

Àkíyèsí: Gbogbo ẹ̀kọ́ oniruuru ẹ̀sìn ni a gbọ́dọ̀ fi Bibeli yẹwò. Bi ẹ̀kọ́ kan kò bá bá Ìwé-Mímọ́ sowọpọ̀, irú ẹ̀kọ́ bẹ́ẹ̀ jẹ́ irọ́ ati wípé ki a pa á tì.

**15.** Kíló ṣẹlẹ̀ nígbàtí Jesu ṣe àlàyé Ìwé-Mímọ́ fun awọn ọmọ-ẹhin Rẹ méjì tí ọkàn wọn dàrú lójú ọ̀nà Emmausi?
**Luku 24:32**
Nwọn si ba ara wọn sọ pé, ________ wa kò ha ________ ninu wa, nígbàtí o mba wa sọ̀rọ̀ li ọ̀nà, ati nígbàtí o ntumọ̀ ìwé-mímọ́ fun wa?

**16.** Lẹ́hìn tí awọn ọmọ-ẹhin meji yi ti mọ̀ pé Jesu yè ati bi wọn ti gbọ́ bí Ó ti nsàlàyé asọtẹlẹ fun wọn, kíni wọn ṣe?
**Luku 24:33**
Nwọn sì dìde ní wakati kan naa, nwọn _________ lọ sí Jerusalemu, nwọn si _______ awọn mọkanla péjọ, ati awọn ti mbẹ lọdọ wọn.

Àkíyèsí: Ohun àkọ́kọ́ ti awọn ọmọ-ẹhin náà ṣe lẹ́hìn ti Jesu ti ṣe àlàyé Ìwé-Mímọ́ fun wọn tán ni wípé, wọn ni ìgbònà ọkàn lati pín ìhìnrere fun awọn ẹlomirán. A nírètí pé, ìpinnu tirẹ náà ni lati pe awọn ọ̀rẹ́ rẹ lati pẹlú rẹ ninu ìpele ẹ̀kọ́ Bibeli yi.

# Èsì Rẹ

Ṣe o fẹ́ lati mọ Ìwé-Mímọ́ ki o sì tẹle e pátápátá?

ÌDÁHÙN: _____________



# Àfikún

Ìwọnyí ni awọn kọ́kọ́rọ́ ti wọn ní ohun ti wọn dúró fun ninú asọtẹlẹ Bibeli. Àmì kọọkan ni a kọ tó hàn kedere ati ìtumọ̀ wọn.

Angeli = Ìránṣẹ́
Danieli 8:16; 9:21; Luku 1:19, 26; Heberu 1:14

Babiloni = Ẹ̀sìn tí kò gbàgbọ́ tabi Ìdàrú
Genesisi 10:8-10; 11:6-9; Ifihan 18:2,3; 17:1-5

Ẹranko = Ìjọba tabi agbara ọ̀ṣẹ̀lú
Danieli 7:17,23

Àkàrà = Ọ̀rọ̀ Ọlọrun
Johannu 6:35, 51,52,63

Ọjọ́ = Ọdún
Esekieli 4:6; Numeri 14:34

Dragoni = Satani tabi awọn ogun rẹ̀
Isaiah 27:1; 30:6 Orin Dafidi 74:13, 14; Ifihan 12 :7-9; Esekieli 29:3; Jeremiah 51:34

Iwájú orí = Ọkàn
Romu 7:25; Esekieli 3:8,9

Ọwọ́ = Iṣẹ́
Oniwaasu 9:10

Àgbèrè = Ìjọ tí kò gbàgbọ́ tabi ẹ̀sìn
Isaiah 1:21-27; Jeremiah 3:1-3, 6-9

Orí = Awọn agbára tàbí olórí tàbí ìjọba
Ifihan 17:3,9,10

Ìwo = Ọba tabi ìjọba
Danieli 7:24; 8:5, 21,22; Sekariah 1:18,19; Ifihan 17:12

Ọdọ Agutan = Jesu tàbí ìrúbọ
Johannu 1:29; 1 Korinti 5:7

Fìtílà Ọ̀rọ̀ = Ọlọrun
Orin Dafidi 119:105

Kìnìún = Jesu Kristi
Ifihan 5:4-9

Àmì = Àmì tàbí èdìdí fun ìfọwọ́sí tabí àìfọwọ́sí
Esekieli 9:4; Romu 4:11; Ifihan 13:17; 14:9-11; 7:2,3

Òkè = Agbára ọ̀ṣẹ̀lú tabi agbára ọ̀ṣẹ̀lú-ẹlẹ́sìn
Isaiah 2:2,3; Jeremiah 17:3; 31:23; 51:24,25; Esekieli 17:22,23; Danieli 2:35, 44, 45,

Òróró = Ẹmí Mímọ́
Sekariah 4:2-6; Ifihan 4:5

Òdòdó = Ẹ̀ṣẹ̀ tabi ìdíbàjẹ́
Isaiah 1:18; Nahumu 2:3; Ifihan 17:1-4

Àpáta = Jesu tàbí òtítọ́
1 Korinti 10:4; Isaiah 8:13,14; Romu 9:33; Matteu 7:24

Èdìdí = Àmì tàbí èdìdí fun ìfọwọ́sí tabí àìfọwọ́sí
Romu 4:11; Ifihan 7:2,3

Ejò = Satani
Ifihan 12:9; 20:2

Ìràwọ̀ = Angeli tàbí ìránṣẹ́
Ifihan 1:16, 20; 12:4, 7-9; Jobu 38:7

Oòrùn = Jesu tàbí Ìhìnrere
Orin Dafidi 84:11; Malaki 4:2; Matteu 17:2; Johannu 8:12; 9:5

Idà = Ọ̀rọ̀ Ọlọrun
Efesu 6:17; Heberu 4:12

Olè = Dídé Jesu lójijì
1 Tessalonika 5:2-4; 2 Peteru 3:10

Àkókò = ọdún kan
Danieli 4:16, 23,25,32; 7:25; Danieli 11:13

Omi = Ibugbé tàbí eniyan, orilẹ-èdè
Ifihan 17:15

Aṣọ funfun = Ìṣẹ́gun tàbí òdodo
Ifihan 19:8; 3:5; 7:14

Afẹ́fẹ́ = Ìjà tàbí ìdàrú "afẹ́fẹ́ ogun"
Jeremiah 25:31-33; 49:36, 37; 4:11-14; Sekariah 7:14

Obìnrin, Mímọ́ = Ìjọ òtítọ́
Jeremiah 6:2, 2 Korinti 11:2; Efesu 5:23-27

Obìnrin, Ìdíbàjẹ́ = Ìjọ tí kò gbàgbọ́
Esekieli 16:15-58; 23:2-21; Hosea 2:5; 3:1; Ifihan 14:4

©2012 Ilé-iṣẹ́ Òtítọ́ Ìyanu
Àṣẹ ati Ẹ̀tọ́ lati tẹ ìwe yi jáde wa fún
Tí a tẹ̀ jade ní ìlú Amẹrika

AMAZING FACTS
P.O. Box 909
Roseville, CA 95678

YOR-SP2.indd 2
12/6/12 9:44 AM